# KINI ERO RE LORI OMO RE

**Lati Owo Alufa M. A, Abinusawa, Mushin**

A... ṣe mi pupọ nigbati mo nwo bi aiye ti nlọ ati bi a... miran ṣe nhuwa si awọn ọmọ wọn pẹlu aironu ra-ra lori awọn ọmọ na ati pe laiṣe aniani ọpọlọpọ ọmọ ... iwe ti o jade ile iwe ni odun to kọja (1965) wa ni Naijiria ti nwọn nwa iṣẹ eyiti ọpọlọpọ awọn Obi wọn ko bikita fun awọn ọmọ na tabi ki awọn ran wọn lọwọ lati ri iṣẹ se tabi fi wọn si ẹnu ẹkọṣẹ.

Ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ wọnyi ni mo ti ngba ni imọran lati lọ ba baba wọn ki awọn si bẹ lati fi wọn sibi ẹkọṣẹ, ṣugbọn ede ti ọpọlọpọ awọn ọmọ na fi nfun mi ni esi ni pe Helbaba wo? baba ti ko ri aye gbọ ti ara rẹ ti ko si gbe ile ni yio ri aye kọ awọn ni iṣẹ.

Ọdun 1965 tun pari awọn miran tun jade ile we, ewo lao ṣe? kini a nro nipa ti Naijiria ti ọjọ iwaju?

Mo bẹ awon Obi lati ṣe itoju awon omo won lati fi won si ona Iṣẹ kiko ti a ko ba ni agbara lati ran won ni ile iwe siwaju si i iṣẹ, Nko le wa ku kli jẹ oye ile baba rẹ. Ti o ba fẹ ni owo gẹgẹ bi ti baba rẹ, bi o na fẹ ran omo ni ile iwe bi ti baba rẹ ti o ba gba imọran lọ kọ iṣẹ.

Mo ṣebi agbajulegun fi ara rẹ fun ọṣi ta pa ni?

# YEYENATU!

## ONIYẸYE EKO

Olotu-Yẹyẹnatu, ...o nki ọ ni Yaba o ko da mi lohun.

Yẹyẹnatu.—Emi kọ.

Olotu Ma nṣeru nko ni sọ fun o o rẹ kẹ.

Yẹyẹnatu: O kere. Bi ẹ ba so ... nko?

Olotu:, O dara kini ṣe ti o ko da mi lohun?

Yẹyẹnatu. Nibo tilẹ ni ni Yaba?

Olotu: O duro lodo okun tin kan bayi ti o nṣe taya moto.

Yẹyẹnatu: Ṣe ni ọjọ Tuesday?

Olotu: Yẹs kẹ.

Yẹyẹnatu: Ha, Ṣebi Taya mọto ọkunrin to fun mi ni lift lo bajẹ

Olotu-Iyẹn ni pe iwọ na ngba lift?

Yẹyẹnatu: Obinrin ti ọkọ rẹ ko ba ni mọto ti ko si gba lift, iya ni o njẹ ọ niyẹn.

Olotu: Iyẹn ni pe Suberu mọ pe iwọ na ngba lift

Yẹyẹnatu: Mo ti wi fun ọjọ ti o ba ra mọto ni nko ni gba lift mọ.

Olotu: O si gba fun o?

Yẹyẹnatu: O gbọdọ gba ni kẹ

Olotu: Ṣe o si tun ngba lift ninu aawẹ yi?

Yẹyẹnatu: Awẹ ni kẹ ṣebi ki iṣẹ ma gba lift. Iwẹ ni emi ki iwẹ ni akoko aawẹ

Olotu: ...inu mi dun dada Suberu ko le fi aawẹ ṣirẹ,

Yẹyẹnatu: Looto ni Nitemi emi ni ko gbọdọ mu; biya dię tabi staut ko buru

Olotu: Ṣe ninu awẹ?

Yẹyẹnatu: Yẹs kẹ

Olotu Iyẹn buru

Yẹyẹnatu: Iyẹn wa buru ti iyawo Alhaji ni?

Olotu: Iyawo Alhaji wo ni yẹn?

Yẹyẹnatu: T... adugbo yin

Olotu: Kini o ṣe?

Yẹyẹnatu: Ni ẹyi ni kẹ

Olotu: ...ni kini o ṣe?

Yẹyẹnatu Emi ni ẹ fẹ ki nwọn fi Ọl pa mi?

Olotu Aṣe Ojo ni ọ

Yẹyẹnat Mo le sọ ọ kẹ igba ti alhaji ni on ko ni gbadun nitoripe on ni awẹ o si jade o lọ gba dun ni tirẹ

Olotu Kini alhaji wa ṣe

Yẹyẹnatu Alhaji ko binu ṣe ẹni Ọlọrun ni

Olotu O maṣe o

Yẹyẹnatu Mo wa sọ fun Suberu pe iru awọn Alhaji yẹn ni o yẹ ki o ma wo fi huwa nitoripe enia daadaa ni

Olotu Suberu ko kuku tẹlẹ

Yẹyẹnatu: Ti Suberu ye kẹ Ṣe o mọ pe ẹniti o fẹ gbajumọ mu oju kuro ni.

Olotu: Looto ma ni iyẹn

Yẹyẹnatu: Nigbati o n w a iṣẹ fun aburo rẹ kan ni ijọsi, ọwọ kan ni mo fi ṣe e

Olotu: Yẹyẹnatu, obinrin mẹta

Yẹyẹnatu: Igbati on na nwa kọntiraki ọ, ko gba mi ni iṣẹju marun

Olotu: Looto ?

Wo oju ewe Karun



ALUFA M. A, ABINUSAWA

gbiyanju lati to omo re yio si fun o ni isimi. Bibeli tun so fun wa pe. Enti o ba toju igi Ọpọtọ yio jẹ eso rẹ. Nigbati Obi kan ko ba toju omo rẹ ti o nfẹ iya wo jo bi o tilẹ bi omo pupo kini o fẹ ki awon omo na jẹ?

Bawo ni o ṣe le ni isimi Njẹ isimi wa fun iru enia bẹ? Ko daju. Bi ọdẹdẹ ko dun bi igbẹ ni ilu ri, toto o ṣe bi owe. Mo bẹ gbogbo ẹnyin obi l a t i ri pe awọn ọmọ nyin bọ si ẹnu ẹkọṣẹ nwọn si yege ninu ẹkọ na nigbana ọwọ kilanko a wa yọ ninu iyan, i s i m i a de fun obi na. Ọlọrun ko ni ṣe ọmọ nyin ni egbe Amin.

### IMỌRAN FUN AWỌN ỌMỌ

Ẹnyin Omọde ti ẹ ṣẹṣẹ jade ile iwe mo fi Ọlọrun bẹ nyin mo fẹ ki ẹ fi eti si imọran awọn obi nyin, ibanujẹ a lopin eti e r u ẹwọn ni fun ọmọ ti ko ni Baba mi lowo ko kan ti aiye is siyi atẹlewọ rẹ ni ogun rẹ wa, ọjọ ti baba ko ni d gi ẹ wọ omi ọjọ ti iya ba k i ni wura rẹ bajẹ Ti o ba nfẹ ki asiko rẹ ni ọjọ iwaju dara lọ kọ iṣẹ ti ko ba si antani lati kọ iwe siwaju si mo.

### ẸKỌ PATAKI

Ẹ jẹki a fi ti baba wa Olori ilẹ Naijiria Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe ṣe ogbọn pẹlu gbogbo iwe ti o mo ṣebi "Printer" ni iṣẹ owo rẹ. Gẹgẹ bi baba orilẹ ede wa yi mo ro pe yio jẹ ẹkọ ni fun emi ati iwọ ọmọ ilẹ Naijiria, T o t o omode ki i pa itan baba rẹ Kabiyesi,

Ko si ohunti a ko le da ti a ba l i ṣ ẹ. Alufa Ọlorun ni emi iṣe iṣẹ "Printer" ni iṣẹ owo mi Ọlọrun ko ni jẹki ilẹ Naijiria bajẹ lo,u wa Amin

Mo ki nyin pe ẹku ọdun O.

# Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

## Mo Kan Saara Si Oba Odẹmo

Olotu, Pẹlu inu didun ati ayọ ni eleyi yio jẹ fun mi bi ẹ ba le tẹ awọn ọrọ mi yi jade ninu Iwe Irohin Imọlẹ to nta bi akara gbigbona lati kan saara si ọba Alaiyeluwa Samuel Akinsanya Odẹmọ ti ilu Isuara nipa aforiti ti o ni ati igbo ya ti Ọba na ni lati sọ ọrọ ti o jẹ otitọ ati opodo lori ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun laiṣe ojusajurẹ mọ.

Mo ro pe eleyi si to fun awọn ọba yoku ti o npe ni awọn baba wa lati fi ti ọba Odẹmo ilu Ishara ṣe ogbọn ki nwọn si fi ṣe iwa nu nipa ọna bi o ti nse nsọ otitọ ti ko titori owo sọ ara rẹ di Bọọlu fun awọn ẹgbẹ Oselu ninu gbogbo ọba inlẹ Iwọ Orun Naijiria ọba ọdẹ ti ilu Ishara ni mo mọ pe ọba se ninu awọn ọba Ipinlẹ na.

Mo ro pe gbogbo awọn enia ilu ti a nti agbegbe rẹ lo san owo ori wọn ti ko si ijafara ninu rẹ lasiko ti nwọn nsan owo ori ati pe a ko mọ ohunti o le fa ti a ko ri omi to dana ti o jẹ lati ẹrọ mu ni ilu na.

Inu awa Olugbe ilu na yio dun bi a ọn Alakoso Ijoba ibilẹ ilu Ijebu mushin ba le tete lo i o wọn rere ki ... si jẹki a ri omi mu lasiko ni ilu na ati pe a ko mọ ohu ti nwọn fi owo ori wa se fun awa enia ilu na nitori eyi ijaluro lewu pupọ a si fẹ ki nwọn tete da ero omi wa na pafun wa ni kiakia.

Emi ni
M. Aiyedun
Ijẹcu—Imushin



Ọba A i sa nya

nyi ọba ti o nbi iwe ibo lasiko idibo to kọja ẹ jẹki eleyi jẹ itiju ati pe ki ẹ lọ mọ daju pe eleyi ko tun ipo ọba sẹlbikose wipe nse ni o ba eto ipo ọba ti o ti wa tẹlẹ jẹ.

Emi ni
Adeọla Adelakun
Abẹokuta

## IJẹbuImushin Nko

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye ran oẹ ninu iwe nyin to kun f n ọgbọn ati oyẹ lati kesi Ijọba ibilẹ ti Ijebu Imushin nipa ẹrọ omi ilu na eviti ti a ni lilo ti awọn enia lu na si ti irọrun ati anfani to pọ lati ri ... mi nọn lasiko t ẹgbe Afẹni fẹr nṣe eto akoso Ijọba Ipinlẹ na ati pe eleyi jẹ ohunti o ya eni lẹnu lati ri pe ẹrọ omi ilu na di ohun ti a ko le ri omi mu nnọn

## Iwa Itiju Ni Eyi Jẹ Fun Naijiria

Olotu: Inu mi yi dun biẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu Iwe Irohin Imọlẹ to kun fun Ọgbọn ati oye lati kesi Alakoso apapọ Ijoba ile Naijiria lati tete lo ipo wọn rere lori ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti ko ti sẹlẹ ni Ipinlẹ kan ri lori abayọri eto idibo to kan lọ yi ti o fi jẹ pe ọkẹsimọye ẹmi ti padanu bayi.

Mo ro pe ohunti o sẹlẹ ni Ipinlẹ na ninu ọdun 1962 ko do idamerin ohunti o nṣẹlẹ yi nigba:i apapọ Ijọba tete ṣe ofin pajawiri si Ipinlẹ na, "leyi t fi han pe ko si Ijọba ododo ni orilẹ ede Naijiria ati pe gbogbo iru ohuntl o nṣele yi ko le fa Iṣọkan wa si arin awọn ọmọ ile Naijiria nitoripe aiṣe otitọ ati ododo ti jẹ ohunti o jẹ ibaje larin ilẹ na

Inu mi yio dun bi awọn enia pataki ti mo darukọ rẹ yi b le lo ipo won rere ki nwọn tete ṣe ofin pajawiri ki nwọn si le awọn ẹgbe oṣelu ti fe fi agbara ṣe Ijọba ti ko ba eto ofin mu kuro lori eto akoso Ijọba Ipinlẹ na.

Olotu e ṣe pupọ fun aye ti ẹ gba mi e ko ni si oro te o.

Emi ni
Benson Oladapọ
ILORIN.

# Ila Kini Eleyi O




OGUN A PA YANMU—YANMU
LORI ERIN META NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ An O dara iu gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si da ra pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu ... yara pa ay ... n ati idun

Tete lo ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si d ... wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun dadara

Kiyesi o ri daju pe ogun yanmuyanmu o ri erin mẹta ... nwọn mu un o

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu eltaja kakiri orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Decemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

# Congreves Female Remedy

(FUN OBINRI)

Ojulowo egbogi fun gbogbo awọn Obinrin boba ba ni iyọnu tabi amodi, Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹko kan ẹhin didun, ibadi-wiwo tabi si an ẹjẹdudu ara tabi a koto ẹjẹ l r nu gbigbona nigbakugba.

Igba aiya riru ọmu riro, didun ara atinu wa ni o ma nfa oyi oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisan, ef ri tabi pẹlu inu ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo Obinrin gegebi Ajo fun ilera ati orisi isi amodi miran ba ma nyọ wọn lenu nigbakugba pelu.

(OLOMI GINLA NI)
BERE EGBOGI TI WỌN NPE NI:—

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba ... ki awọn Orişirış robirobi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba alaye atijọ mọ daju wipe kosi ohuntl o le fi we egbogi yi bi otutu, Iko, Iba, Ọrere, Lukuluku, Onigb meji tabi aiperi nyọ enia lenu yala Ọm de tabi Ag algba ni yio ṣe iwosan rẹ bi d ni ga ni bi o ba ti ta de sinu omi ti o lọworo k o si gbemi bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun a tu Akokoro egbogi ti o ma nfọ apo ile itọ tabi ṣe iwosan dọnu apo ile itọ egbogi oju ddun tabi ti ona ofuu di dun ati orişirişi omiran pelu won mbe ni ṣọbu awo :

# Awọn Ọmọ Alhaji Awaiyewaṣere ṣe iranti Baba wọn

EKO;— Ni ojo Abameta ti iṣẹ ọjọ kedọgbọn oṣu kejila ọdun 1965 ni awọn ọmọ oloogbe Alhaji James Asani D su Z Q ti apele oruko re nje "Alhaji Ashton Ki der" tabi Alhaji Awaiyewaṣere ṣe akanṣe adura fun Baba wọn na,

Ẹsẹ awọn Lemọmu ati awọn Alhaji ati awọn gbajumọ ni o si pe ṣọṣọ si ibi akanṣe isin iranti na, ni ile Baba Oloogb na, "11/13, Upper King Street" l'Eko Alhaji Imam Mohammed Munaru Deen Agor ni o si ṣe olori Isin na. Hadji Imam na mo kewu pe pupu ẹnu rẹ dun Ni gbogbo ọna ni o si fi yanju.

O ni eni ire ti o si peye ni oloogbe Alhaji Awaiye wasere o ni o y w pupọ o ni ọyaya pupọ o josin pupọ o si m a ngmọ toni toni at igba aiye rẹ o ni lakaye pupọ o si f ran t ja te an o se adura fun i pupọ awọ ọmọ oku a si na wa bi wọsi owo titi aseye is'nku na dun o larinrin irohin ko to afojuba ni o si jẹ

D e ninu awọn ọmọ oku na ti o pese sibe ni Hadja Iyaafin R a Gbajabiamila Iyaafin Mini A Giwa Hadji Y A D s Iyaafin R Kasun mu on le la Iyaafin Aditu Iyaafin Tayibatu D su awon Ọgbẹni

Shakiru Akinola Disu Muniru Disu ati Tajudeen Disu ki Ọl un kẹ ku na ki o si gẹẹ, ki o si jẹki ehin rẹ dun ju oyin lo ki Ọlọrun si fi awon ọmọ ire gbhin awọn ọmọ oku na, ni gbati nwọn b dagba daru gbo isin

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22—Feb 20) Maṣe nawo ni ina kuna ki o ta le dara fun ọ lojo iwaju igbati owo miran ba tun de

PISCES (Feb 21—Mar 20) Alafia yio de si ọ, ara rẹ yio si le giri iri, tobẹ ti iwọ yio nitẹlọrun lọna gbo gbo, larin ile, orẹ ati ebi, bi o ba si ri ọ a titun ti enia le fi ba won maṣe jafara.

ARIES (Mar 21—April 20) Maṣe da iṣẹ rẹ ru masi ṣe jeki o pa ọ laiy o san ki o kuku din Iṣẹ ti o ṣe lojọ ku ki are ma ba mu ọ ki gbogbo iṣẹ rẹ ma ba daru

TAURUS (April 21—May 20) Are fẹ mu ọ ṣugbon o yẹ ki o le gba ara rẹ silẹ o si ye ki o l fi ara lelẹ tabi ki o sun.

GEMINI (May 21—June 21) Ọjọ oni dara, e r o ọkan rẹ si dara pẹlu, ṣugbon inawo airotẹlẹ yio de si ọ, akoko aṣalẹ yio si miringindin fun o iwo yio si gbadun awon alejo ti o wa ki ọ.

CANCER (June 22—July 22) Iṣẹ ti o fẹ ṣe loni yio pa arẹ ni y o si pakun rẹ fun ọ, da awon Iṣ ti o ku duro ki o si lọ fi ara lel :

LEO (July 23—Aug 22) iwọ ko ni ọyaya s enia, nitori ki o fi ara mo ohunkohun ti o ba de, ṣugbọn ki o ma ṣe ọmọ'a.

VIRGO (Aug 23—Sept 23) Igbehin ohun ti o da silẹ yio dara, iw yio si tun ri nk n iyanu lati ọdọ awọn ọrẹ ati ebi wa

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Gba ara rẹ kuro lọwọ amodi ti o nfẹ ṣe ọ, sibẹ ire mbẹ fun o loni

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Boya o te ṣe akiyesi wipe orọ ara rẹ ko lọ deede mo bi o ti ni lati lọ, ki o ṣe suru ki o si jeki o ye ọ pe, ko ni pẹ ka kuro.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Ki o dupe lọwo ero rẹ ti o pe iwọ yio ri ire, aṣiri rẹ si bo gbogbo ohun ti iwọ ko ti ri aye lati yanju ni o ki o mojuto

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Oro awọn ebi rẹ ni telorun, ṣugbọn sibẹ arẹ s mbẹ lara rẹ, o ye ki o fi ara lelẹ, ki o si din iṣẹ rẹ oni ku ki o ba ri aye simi


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYNAMIREN** TONIKI



ALE-BI-ALE Egbogi Tọ i iamọnu, tilun ti gbogbo a Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ dẹ fun Agbara ati Ajẹbidan ṣẹ lara agbalagba Ọkunrin ati Obinringbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan l san tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ka ṣefun daradara ti Emi Breath inu o ba kuẹ lẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi nu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si aderi tabi ubẹ lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lari sọ ara di tu patapata inu rẹ a jọlọ ẹran ara rẹ ti o g hunjọ yio bi yabo dada tiAra rẹ yio gbe kankan i agba yio sao pẹlu ioq m udeu brode iyẹn d b ṣ

Waterloo Medicine Stores
8 Palm Church Street Lagos

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street Lagos
Phone 22878 Nigeria (O a Ina Fiji)
LAGOS



BERE FUN OJULOWO ADI ELEGBO

# "Congreve's odo Form--Ointment'



Atamatase ni egbogi " ADI-ELEGBO" yi i fun itọju egbo gbo oriṣiriṣi "EGBO—ESẸ" ni kakiri bi o ti wun ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi k ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọ i ni bi ẹrigbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio su mo daradara .Lẹhinna oju egbo ti o ba jin si u yio je i oju re ru wa soke, y o si pọn daradara ran hakaru ko si mọ acrewere ni yio si sao patapata Alafia de si ọ niyen :

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si sale iwe yi ni egbe ranṣe lọ ra Bibeko awọn Eleru abi enijibiti yio ta 'Adamedi' re fun o m se gba r ro.

Bere egbogi yi ṣobu awon :—ọ

ADEDUN CHEMIST
14, Waseman Street, Yaba

Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Streer Lagos P O Box 333
ATI NI ṢOBU
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

# OJUBO ORIṢA OKE IBADAN

Ọkan ninu awọn Oniwe Irohin wa lo lọ ṣe abẹwo ojubọ Oriṣa Oke Ibadan nilu Ibadan, iwọnyi si ni irohin ti o muwa fun wa,

Nigbati mo de ibẹ, ohun ti nwọn kọkọ fi ko mi lọna ni wipe ki nbọ bata ẹsẹ mi kuro ki nto wọ igbalẹ Oke Ibadan nibiti nwọn ti mbọ Oke Ibadan paapa mo si lọ tara Aboke ẹniti oruko rẹ njẹOloye Ọlaogun Abọke

O fun mi ni itan Oriṣa na bayi pe Obinrin ni Oke Ibadan ti o si ti nṣe iranlọwọ fun ilu Ibada l na gbo gbo Onişowo ni Oke Ibadan se nigba aiye re lehin iku awọn ara

Ibadan yi ọjọ kan sọtọ lati ma ti ṣe iranti rẹ ni ilu iṣẹ ilọiribi ti o ti ṣe larin wọn ni gboro ilu Ibadan Awọn nkan ti nwọn fi nṣe etutu rẹ ni Malu Aja, Ewurẹ, obi ati igbin

Loto ti nwọn ba mbọ Oke Ibadan awọn obinrin yio ko ara wọn jọ bi iwọn irin o enia, ti nwọn o si ma kọ orin is kuso ti ko dara lati ma kọ Ọkan ninu orin na ti o ṣe gbọ si eti nyi:

Iya ma ba mi wi,
Aboke i mi ba rode
Nigbati mo nfẹ tesiwaju ninu Igbalẹ na, Aboke ṣe kil fun mi nko gbọ k ja ibiti mo de yi hi mo ba si lo agidi ti mo gbe ẹsẹ kan siwaju si, afẹku si yio ba oluwarẹ iyẹn nipe oluwarẹ yi pora oniwe Irohin wa bẹ re pe kini ohuntio wa ni ibi ti enia ko gbọdọ de na Abọkẹ dahun pe ko si oriṣa tabi ohun kan nibẹ aşiri, ti o wa nibẹ ni pe nibe Oke Ibadan gbe nfi ara han, on nikanşoşo n o nti ti nwọn sijumọ mba ara wọn sọrọ

O to iwọn ọdun mẹsan ti on ti joye Aboke Oko si on nro ki nwọn to wa fi on jẹ oye yi nitori oye na jẹ oye iran o sọ pe iran mẹdo gbọn nwọn nfun on ni ọdọdun kere pupọ fun on, Iran on ni yio si ma joye Aboke titi lailai.

# Ọmọ Egbẹ Dẹmọ Nfẹ Apapọ Dẹmọ Ati Afẹnifẹre

IBADAN: Lati igbati nwọn ti dibo si Ipinlẹ Iwọ Orun ninu kiwa ọdun yi ni awọn die ninu ẹgbẹ Dẹmọ ti nmẹnu kan pe awọn nfẹ ki ẹgbẹ Dẹmọ papọ mọ ẹgbẹ Afẹnifẹre, O fẹrẹ jẹ pe ni ojojumọ ni a ngbọ ti egbe Demo nfẹ apapọ ẹgbẹ Afẹnifẹre pẹlu ẹgbẹ Dẹmọ,

Bẹnani gbara ti ẹgbẹ Afẹnifẹre wọle jaturata ninu ibo ti nwọn di ni ọjọ kẹtala ti kọja yi sile Igbimọ Ijọ a Ibilẹ ilu Ekọ ni awọn ọmọ ẹgbe Dẹmo ti ndupẹ lowọ awọn ara Eko, paapa Oloye Ayọ Rosiji ni on mọ pe, ẹgbe Afẹnifere ati Demo yio tun papọ, nitoripe edeaiyede ni ko ni pe pari

Ninu iwe kan ti ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti o wọle agbegbe Ọshun Ọgbẹni Ganiyu Abodude, ti o tun jẹ amugbalẹgbẹ fun Minista eto Alafia arin ilu kọ ni ọjọ Aje ọjọ kẹfa oşu tokoja oni ẹna tun fi ẹnu kan pe a fi kẹgbẹ Dẹmọ ki o papọ mọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni nkan gun rege,

Ọgbẹni Abolude fi ẹnu kan pe iṣọkan awa Yoruba ni a leni bi gbogbo wa ba wa ọkan ṣoṣo ti a si nfi ifẹ ba ara wa gbe papọ ti a ba tun nṣe ilu wa fun arawa ti a ba kọ lati ma a gba aṣẹ nihin ati lọhun nitoripe ifẹ ti nwọn ni si wa nipe ki nwọn pa wapọ lati fi di ọba mọ lori ti nwọn yio ma a pa aṣẹ le wa lori.

O wa pari ọrọ rẹ pe oogun ti awa Yoruba le fi ni ìẹ aiṣẹtan ati ifẹ ti yio so gbogbo wa pọ di ọkan ṣoṣo koju ki a fi ọwọ arawa tun nkan arawa ṣe lọ.

# YẸYẸNATU!

## Lati Oju Iwe Keji

Yẹyẹnatu: K o d a igbati ẹgbọn Laba rẹ k a n nwa oye ni ijeelo, mi i onu si Ifẹ ko si, mo foonu si Ibadan ko si mo foonu si Ijẹbu ni Agọ Iwoye ko si, ṣugbọn ilẹ ọjọ yẹn ko ṣu ti mo fi r ọkan f u n

Olotu: Ha-a! Yẹyẹnatu, opurọ ni ọ

Yẹyẹnatu: Emi, opurọ, ẹ bere lọwọ Suberu kẹ

Olotu: Aai irọ ti lọ rẹ ni ifun. Abajọ awọn le ọ ni Ibadan

Yeyẹnatu: Şeol awọn ara ile Suberu lo jẹ ki nwọn le mi.

Olotu: Ewọ na yaju si wọn ni ?

Yẹyẹnatu: O r i nwọn lo buru

Olotu —Tani yio ha tunşe bayi o

Yẹyẹnatu—Emi ko mọ Ẹjọ tiwọn ni iyẹn

Olotu O ma ninu si wọn

Yẹyẹnat Nko şe ni binu? Şebi ẹnyin na mọ pe nko le ni Ibadan sire tẹtẹ

Olotu Ẹnu tirẹ na ti mu ju

Yẹyẹnate Ẹnu mi mu to ẹ u baba lo dan ni

Olotu Baba Ibadan wo?

Yẹyẹnatu Alhaji Jinadu

Olotu Emi soma mọ iyo ku

Yẹyẹnatu H lẹ ko mọ ba ba sọ mi

Olotu Hẹwu, igba wo ni nwọn lọ si aaji kẹ?

Yẹyẹnatu Awọn moşalaşi kan ni ilẹ Hausa ni o ma fun wọn ni oye Alhaji

Olotu Ha! Yẹyẹnatu opurọ

Yẹyenatu Looto ni, nwọn nitori pe nwọn ti gba Olori esin Imale ni ẹga Kuda ọjọ na ni nwọn sọ wọn ni Jinadu

Olotu Ani ko ye purọ

Yeyenatu Nko ro pe on abagbọ ni yin şa? Kini ẹnyin tile le gbagbọ la iyẹ si ?

Olotu Otitọ ni mo le gba gbọ

Yẹyẹnatu O dara otitọ ni mo le gbagbọ Mohamadu ni adiresi, Şe o gbagbọ

Olotu Yes mo gba gbọ

Yeyenatu Ẹnyin na ko ni pe di Alhaji

Olotu Bawo?

Yeyenatu Jesu ko ni adiresi

Olotu Iṣọkuṣọ ọrọ odi ni o tun nsọ yi o

Yeyenatu Ha, e ko le di alhaji ninu iyen o, O digba


# KERE O!

Nje o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA' to şeşe jade ?

Ha! Kosemani ni Iwe ni jẹ fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan şẹdalẹ Yoruba, Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ . Maşe jẹki nwọn rohin itan ilu rẹ fun ọ

3/- pere ni. Postage 9d

Tete f'owo tirẹ ranşẹ si;

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Ijumagbo Avenue Lagos Nigeria
( Leti Oja Jankara )


Ẹ ma a ka we Irohin Imọlẹ Ki ẹ si maa Polowo Ọja Nyin sinu rẹ Lojojumọ

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,600 SATURDAY JANUARY 1, 1966 (2D)


## Omo Kan Şa Iya Rẹ Pa L'Oju OOrun

ABẸOKUTA:- Oro di pọntuka, gbogbo enia si bẹrẹ sare ọlọmọgbẹmi pọn ayọ ti Odarin omo kan, *remo, eni odun mẹdọgbọn sare wọ inu iyẹwu re ti o si ti ọbẹ su si ti o si aşọ loju iya na, ti o si gun un ni ọbẹ l'orun gẹgẹbi igba ti enia yio ba du nbu eran Ileya ni ọjọ Abamẹta ti ọjọ kẹdọgbọn osu yi ni ọjọ ọdun Keresimesi.

Enia ti o sọ fun wa alaye Oniwe Irohin wa ni Abẹọkuta ni ojo na wipe, ni abuleko kan ti nwọn npe ni Elere, ọna kan ti ko jinna pupọ si Ilori ni eti Abẹọkuta ni ọrọ na ti şẹlẹ, nibiti gbogbo awọn enia wọle na ti nyọ ayọ odun Keresimesi, ti gbogbo nwọn njo, ti nwọn si nyọ, lojiji ni awọn gbọ ariwo ti o fa ọbẹ nigbati awọn si de ibẹ ni awọn ba ọbẹ lọwọ Odaran ọmọ na ti o si gun iya rẹ pa bamubamu.

Nigbati omọ na wọle lati ode ti o lọ, ti o si fẹ wọle lọ ba iya rẹ, o ni awọn lero wipe o fẹ lọ ki iya rẹ ku ile ni a fi igbati awọn ngbọ ariwo ni ojiji ti iya na njarapa nile ninu agbara ẹjẹ şugbọn gbogbo bi awọn ti şe tọju iya na to ni ojo na, o ku ki awọn to gbe de Ile Iwosan ni awọn lo fi ọrọ ba awọn Ọlọpa 'tori.

Okan ninu awọn enia na sọ fun Oniwe Irohin wa wipe, awọn lero wipe omọ na mu ọti yọ ni, ko wa mọ ohunti o nşe mọ, şugbọn awọn Ọlọpa ti mu Odaran ọmọ na lọ si Tesan, fun iwadi ọrọ, nwọn si ti gbe oku iya rẹ lọ si Ile Iwosan lakulaku fun'iyawo; awọn Dokita, a lero wipe omo na yio farahan niwaju adajọ ni kotu ti işe ọjọ kẹta oşu yi.

# AWỌN KAN DANA SUN TIMES ATI POST

IBADAN:- Ni kutukutu owurọ ọjọ ọjọ Ru ti işe ọjọ kọkandinlọgbọn oşu yi ni awọn enia kan lọ dana sun ile Işẹ iwe irohin "Daily Times ati Morning Post" ni ilu Ibadan eyiti o jẹ wipe gbogbo awọn ohunti nwọn nlo ninu ẹka ile işẹ na ni awọn enia na ko ri aye pana sun lori ibosi ti awọn enia to nşọ awọn ile işẹ iwe irohin meji na ke eyiti awọn enia na si salọ.

Lẹsẹkẹsẹ na ni awọn enia tu ngbe ni adugbo na yara tete sare de ibẹ, ti wọn si tete pana to nṣo ninu awọn ile işẹ iwe irohin meji na.

Oniwe irohin wa fi ye wa pe awọn iwe irohin "Morning Post" ti nwọn di si ọna marun ati iwe irohin "Daily Times" eyiti gbogbo rẹ jẹ ẹgbẹwa (2,000 copies) ni a gbọ wipe o jona patapata.

Alukoso eto ọna bi nwọn ti npin awọn iwe irohin na ati Olutawe irohin na to wa nibiti işẹl, na ti şẹlẹ ni a ti gbọ wipe awọn enia na koko le wọn lọ de ibiti o jinna diẹ ati pe awọn enia na si sa asala fun emi wọn ki awọn enia na to dana sun awọn iwe irohin 'Morning Post"

Oniwe irohin wa fi ye wa nipa irohin re pe ko si ni pupọ na ni awọn panapana ti ilu Ibadan de sibi ile işẹ na ti nwọn si ba awọn enia to wa şe iṣẹ nlọwọ fun ọkunrin Aşẹde ile işẹ iwe irohin na, şugbọn awọn panapana ni tete yara pa ina na

Ko si pe pupọ na ni awọn ọlọpa tun de si ile işẹ iwe irohin "Daily Times ti ilu Ibadan ati pe awọn ọlọpa ti bẹrẹ lati ma şe iwadi ohunti o fa ina na ati pe ko si enia kankan ti awọn ọlọpa ri mu ninu awọn enia na.

Ni ọjọ Işẹgun ti işe ọjọ kejidinlọgbọn oşu to koja lọ yi ni Ijọba ibilẹ ilu Ibadan şe ofin ti nwọn fi de awọn iwe irohin ti o jẹ ti ile işẹ ti "Daily Times" pe ko gbọdọ wọ ilu Ibadan tabi pe ki nwọn ti lọwọ enia ki nwọn ma ka ni ilu na eyiti o jẹ wipe Ijọba ibile na tun şe ofin pe enikẹni ti o ba ka awọn iwe irohin na yio lugbadi ofin Ijọba ibilẹ ilu Ibadan

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe ni ojo karun oşu kokonla odun to koja lo yi ni Ijoba Ibilẹ ilu Ibadan şe ofin pe ki awọn iwe irohin marun kan eyiti irohin Imolẹ wa ninu won pe ko gbodo wo ilu Ibadan tabi pe ki nwọn ka iwe irohin na ni arin ilu Ibadan.


## Asalama Alaikum Jammah !

### Nafila Oru Oşu Ramadan.

Lati Owọ ALUFA AKEWULA

ORU OJỌ KEWA 1/1/66 : Irun mẹrin, Salamo meji lori iduro Irun kọọkan, ẹo ke Fatiha kan; Ayatal Kursiyu kan, ina anzalinahu kan ati Kulihau-Allahu mejila

KA IROHIN—IMOLẸ FUN NAFILA TI OTUNLA


## Lati Oju Ewe Kini

O tun şe alaye pe ẹjẹ awa o ni ti o ni ilẹ alawọ dudu ti a si jẹ ọmọ ilẹ Afrika le gbe pọ bayi gẹgẹbi ẹgbọn ati aburo larin ara wa.

Ọlọla Dokita Orizu tun şe alaye pe ilẹ Naijiria ni o jẹ ile kan şoşo ti o le wa gẹgẹbi ẹgbọn ati aburo si ara wọn nipa ẹmi işọkan to wa larin awọn enia ilẹ na. O tun şe alaye pe bawo ni a le şe gbiyanju ti orilẹ ede wa ti işe Naijiria ki yio şe kẹta ni ilẹ Afrika ati ni orilẹ ede agbaye lori ọna bayi?

O ni ohunti o tọ ti o si ye olukuluku awọn ọmọ ile Naijiria lati şe ọna ni nwọn yio ti şe le şe wa is kanʼsi ile wa ti işe Naijiria. O tun şe alaye pe ẹhin ọla ilẹ Naijiria si wa lọwọ awa ọmọ ilẹ na.

O tun şe alaye pe otitọ ni enia le ma şe fun awọn Ijọba Oselu ni ilẹ Naijiria o ni gbogbo wa si nşişẹ na fun eto ilọsiwaju ilẹ Naijiria ni pupọ o ni nitori idi eyi ni o ni lati ni isowọpọ lati wa ẹmi işọkan si ilẹ wa

Ọlọla Dokita Orizu tun şe alaye pe on kan saara si awọn Olori ilẹ Naijiria lati e fi idi ijọba rere mu lẹ ati pe fun eto ilọsiwaju nipa işọkan ilẹ Naijiria lori ona eto ofin.

Bakanna ni Ọlọla Nwafor Orizu tun kan saara si awọn ọmọ ogun ti ilẹ Naijiria awọn ọlọpa. awọn Adajọ, awọn Amofin ati awọn Oşişẹ Ijọba lori işẹ ribiribi ti nwọn şe fun ilọsiwaju ile Naijiria.

Nipari ọrọ re Ọlọla Dokita Nwafor Orizu tun ki gbogbo Olugbe ilẹ Naijiria pe ki nwọn ku ọdun o si gba adura pe ọdun yio ya abo ati pe Olorun yio si ran Olukuluku lọwọ. Otun gba adura pe ilẹ Naijiria yio si ma ni ilọsiwaju si i ati pe ẹmi işọkan yio si wa larin awọn Olugbe ilẹ na awọn Orilẹ ede kan eyiti o şe alaye ni ọdun 1961 A o orilẹ ede agbaaiye şe eto kika awon enia ilẹ Chinaşi 669,000,000, India 438,000 000 Germany 70,000,000 U S S R 214,000,000 o tun alaye pe ko si ninu ile Afrika ti awon enia rẹ to 100,000,000


Printed & Published By Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 1/1/66